U.S. Department of Justice
Federal Bureau of Investigation

# ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌDÁHÙN SÍ ÌHÀLẸ̀ ÀTI ÌDẸ́RÙBÀ

## ÌHÀLẸ̀ OJÚKOJÚ

**Ìhàlẹ̀ ojúkojú ní ti ara ní ìgbà tí ìwọ bá wà nínú ewu to súnmọ́ nítorí ìsúnmọ́tòsí ẹnití ó se Ìhàlẹ̀ na. O ní àwọn àsàyàn mẹ́ta:**

1. **Sá'ré:** Mọ ìpa ọ̀nà àbáyọ. Kó àwọn ohun ìní tí ó lè fa àìyára rẹ sílẹ̀. Tí ó bá seése, kí o ran àwọn míràn lọ́wọ́ láti rí ọ̀nà àbáyọ. Pe ẹ́ẹ̀sán, oókan, oókan.
2. **Fi ara pamọ́:** Fi ara pamọ́ kúrò níbi ìdojúkọ Ìhàlẹ̀. Ti àwọn ilẹ̀kùn tàbí kí o dí àwọn ọ̀nà àbáwọlé. Kí fóònù rẹ wà ní ìpalọ́lọ́ (pẹ̀lú ní ipò gbígbọ̀n) àti kí o wà ní ipò ìpalọ́lọ́ títí di ìgbà tí Ìhàlẹ̀ bá ti tán.
3. **Jà:** Ìjà gbọ́dọ̀ jẹ́ ohun àsekẹ́yìn àti nígbàtí ẹ̀mí rẹ bá wà nínú ewu to súnmọ́ nìkan. Gbìyànjú láti jẹ́ kí Ìhàlẹ̀ di àìlágbára. Se ise pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìfaraya bí ó ti seése

**ÌHÀLẸ̀ ÌFẸNUSỌ OJÚKOJÚ èyí tí kò fi olùgbà sí ewu lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tàbí ní ìgbìrò láti se nígbàmîì**

- Sàkọsílẹ̀ tàbí bíbẹ́ẹ̀kọ́ se ìgbàsílẹ̀ Ìhàlẹ̀ gan-an bí wọ́n ti sọ́.
- Se ìgbàsílẹ̀ bíí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn àpèjúwe àlàyé bí ó ti seése nípa ènìyàn tí ó se Ìhàlẹ̀ náà: orúkọ, ìrísí, àwọ̀ ara, ìmọ akọ tàbí abo, gíga, ìwọ̀n, àwọ̀ irun àti ojú, ohùn, asọ, tàbí èyíkèyí ẹ̀yà tí ó yàtọ̀.
- Se ìfisùn Ìhàlẹ̀ fún agbófinró

## ÌHÀLẸ̀ LÓRÍ FÓÒNÙ

**ÌHÀLẸ̀ LÓRÍ FÓÒNÙ jẹ́ Ìhàlẹ̀ tí a gbà lórí fóònù. O gbọ́dọ̀ se akitiyan láti gba ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àlàyé lórí olùpè àti Ìhàlẹ̀ bí ó ti seése, àyàfi tí Ìhàlẹ̀ bá wà nítòsí tàbí lè se ìpalára fún ìwọ tàbí àwọn míràn lọ́wọ́lọ́wọ́.**

- Wà ní ìfarabalẹ̀ àti kí o máṣe gbé fóònù sílẹ̀.
- Jẹ́ kí olùpè wà lórí ìpè pípẹ́ bí ó ti seése àti se akitiyan ìbẹ̀bẹ̀ fún àlàyé láti mọ̀ bóyá Ìhàlẹ̀ jẹ́ pàtó, òótọ́, tàbí lè fa ewu fún Ìwọ tàbí àwọn míràn lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Tí ó bá seése,se àpẹrẹ ìfiyèsí fún àwọn míràn tí ó wà nítòsí láti fi etí si àti fitó agbófiró létí
- Sàkọjáde èyíkèyí àlàyé tó hàn lórí fóònù.
- Kọ ọ̀rọ̀ ìhàlẹ̀ náà bí ó ti rí gan-an.
- Se ìgbàsílẹ̀ ìpè náà tí ó bá seése.
- Ní àyè láti se ìjíròrò àwọn àlàyé pẹ̀lú àwọn òsìsẹ́ agbófinró.

## ÌHÀLẸ̀ LÓRÍ ẸRỌ ÀTẸ̀JÍSẸ́

**ÌHÀLẸ̀ LÓRÍ ẸRỌ ÀTẸ̀JÍSẸ́ jẹ́ ìhàlẹ̀ tí a gbà nípasẹ̀ ìfiránsẹ́ tààrà, íméelì, tàbí àwùjọ ayélujára. Ó lè pẹ̀lú Ìhàlẹ̀ ìbanilórúkọjẹ́ tàbí àbájáde búburú tí olùgbà kò bá wà ní ìbámu.**

- Má se sí ẹ̀rọ àtẹ̀jísẹ́ tàbí àsomọ́ láti ọ̀dọ̀ olùfiránsẹ́ àìmọ̀.
- Má se ní ìbásọ̀rọ̀ lórí àwùjọ ayélujára pẹ̀lú ẹnì  àìmọ̀ tàbí tí kò bẹ̀bẹ̀.
-  Ri dájú pé àwọn ètò àbò ní o fi sí ìpele ìdábòbò tí ó ga jùlọ

**Tí o bá gba ìhàlẹ̀ lorí ẹ̀rọ:**

- Má se pa àtẹ̀jísẹ́ náà rẹ́. Àyẹ̀wò oníwàdí lè wú àwọn àlàyé pàtàkì jáde.
- Sí àtẹ̀jísẹ́ náà sílẹ̀ lórí kọ̀mpútà.
- Fitó agbófiró létí lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Se àtẹ̀jáde, àwòrán, tàbí kọ àtẹ̀jísẹ́, kókó ìlà, ọjọ́, àti àkókò.
- Se ìtọ́jú gbogbo ẹ̀rí orí ẹ̀rọ

## ÀWỌN ÀKỌLÙ AYÉLUJÁRA

**ÀKỌLÙ AYÉLUJÁRA lè gba ìbọ̀dè wá sí orí ẹ̀rọ àti se àfihàn àlàyé nípa rẹ.**

- Lo gbólóhùn ọ̀rọ̀ ìgbaniwọlé tí ó gbóra àti kí o má se lo irú gbólóhùn ọ̀rọ̀ ìgbaniwọlé tí ó jọra fún àwọn orísirísi  ayélujára
- Se ètò ohun èlò ìmúdójúwọ̀n láìfiọwọ́yi tí ólòdì sí ọlọ́je àti tí ólòdì sí kòkòrò.
- Fi ìmúdójúwọ̀n ẹ̀rọ àti àmúlò inú kọ̀mpútà si ní kété tí wọ́n bá ti wà.
- Fi ìfàṣẹsí ní ọ̀nà méjì..
- Se àfẹ̀yìntì nígbàgbogbo

**Tí ìwọ bá fura pé ìwọ jẹ́ olùfaragbá àkọlù ayélujára:**

- Má se pa àwọn ètò inú kọ̀mpútà rẹ tàbí pàrọ̀.
- Kàn sí àwọn àgbékalẹ̀ ìsètò ìnáwó rẹ láti dábòbò àwọn àkọsílẹ̀ ìwé owó rẹ lọ́wọ́ olè ìdánimọ̀.
- Yí  gbólóhùn ọ̀rọ̀ ìgbaniwọlé padà àti se àbójútó àwọn àkọsílẹ̀ ìwé owó fún àwọn ìse tí ó ní ìfura.

***Tí ìwọ bá wà nínú ewu ara lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ pe: ẹ́ẹ̀sán, oókan, oókan.***

*Tí ìwọ bá ní ìrírí ìhàlẹ̀, jọ̀wọ́ kànsí FBI ti ìbílẹ̀ rẹ (àtòjọ wa ni www.fbi.gov)*
*tàbí se ìtalobó sí 1-800-CALLFBI (or 1-800-225-5324) tabi si www.fbi.gov/tips.*
*Ìwọ́ tún lè se ìtalobó aláìlórúkọ lórí fóònù tàbí ayélujára sí FBI*

U.S. Department of Justice
Federal Bureau of Investigation

# ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌDÁHÙN SÍ ÌHÀLẸ̀ ÀTI ÌDẸ́RÙBÀ

## Tani kí n básọ̀rọ̀ tí mo bá ní ìrírí ìhàlẹ̀ tàbí ìdẹ́rùbà: Ọlọ̄pa ìbílẹ̀ tàbí FBI?

- Tí ịwọ tàbí àwọn míràn bá wà nínú ewu ìpalára lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, pe Ọlọ̄pa ìbílẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀ẹ̀sán, oókan, oókan.
- Tí ìwọ bá ní ìrírí ịhàlẹ̀ tí ó papọ̀ mọ́ ọ̀ràn ìjọba àpapọ̀, kànsí ọ́fìisì FBI ti ìbílẹ̀ rẹ (àtòjọ wa ni www.fbi.gov) nípa pípè 1-800-CALLFBI (tàbí 1-800 -225 -5324) tàbí ni www.fbi.gov/tips. Àwọn àpẹrẹ ni ìhàlẹ̀ láti ọ̀dọ̀ asojú ìjọba orílẹ̀ èdè míràn, ọ̀ràn tó létò, tàbí òsìsé ìjọba. Ìfisùn rẹ lè jẹ́ aláìlórúkọ.
- Kìí se gbogbo àwọn ìsẹ̀lẹ̀ ló ní ìbámu pẹ̀lú ìpele ìsẹ̀lẹ̀ ìsèwádìí ti FBI. tí ó bá jẹ́ ìwọ ni olùfaragbá ìsẹ̀lẹ̀ tí kò sì ní ìbámu pẹ̀lú ìpele ìsẹ̀lẹ̀ tí ọ̀ràn ìjọba àpapọ̀, o lè se ìfisùn sí ẹ̀ka Ọlọ̄pa ti ìbílẹ̀ rẹ. Sàkání agbára ìpínlẹ̀ àti ìbílẹ̀ ní orísirísi àwọn ìpele ìsẹ̀lẹ̀ fún ìwádịí àwọn ẹ̀ ọ̀ràn ìfurasí.

## Kíni mo lè retí tí FBI bá se ìfọ̀rọ̀wánilénuwò fun mi?

- Asojú FBI lè pàdé rẹ ní ọ́fiísì FBI tí ó wà ní agbègbè tàbí ní ibi mìíràn.
- FBI nàá máa bèrè pé kí pèsè ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àlàyé bí ó bá seése nípa ọ̀daràn àti àwọn àlàyé ìhàlẹ̀ tí ìwọ ní ìrírí rẹ̀.
- FBI nàá máa bèrè fún àlàyé ìkànsí rẹ láti tẹ̀síwájú pẹ̀lú rẹ tí ó bá nílò.
- FBI nàá máa gbìyànjú láti dábòbò ìdánimọ̀ àti àwọn ohun àsírí rẹ.
- Tí ó bá bójúmu, alámọ̀já olùfaragbá ti FBI lèwà nígbà ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò láti pèsè àlàyé àti àtìlẹ́yìn, tàbí kí wọ́n kàn sí ọ lórí fóònù tàbí méèlì lẹ́yìn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò rẹ

## Kíni ìpele ìsẹ̀lẹ̀ fún FBI láti se ìwádìí ẹ̀dùn ọkàn àti/tàbí bíbẹ̀rẹ̀ ìsèwádìí?

- FBI nàá lè sèwádìí ìhàlẹ̀ tí ó rú òfin ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀ èdè US tí ó túmọ̀sí ìpalára tàbí ewu fún olùgbà.
- Agbára ìjọba orílẹ̀ èdè US láti se ìpẹ̀jọ́ àwọn ènìyàn fún ẹ̀sùn tí ó jẹmọ́ ìhàlẹ̀ ní ìgbáralé àwọn orísirísi okùnfà, bíi dídára ẹ̀rí, agbára láti se ìdánimọ̀ àwọn ẹni tí ó se ìse nàá, fífi ìdìtẹ̀ nàá hàn, àti/tàbí agbára láti mú àwọn ẹni tó dá ọ̀ràn.

## Kíni mo lè retí tí FBI bá se bíbẹ̀rẹ̀ ìsèwádìí?

- Tí FBI bá gbàgbọ́ pé bóyá wọ́n ti dá ọ̀ràn ìjọba àpapọ̀, ọ̀kan tàbí díẹ̀ nínú àwọn asojú pàtàkì tí FBI máa se ìwádìí. Bí ara ìwádìí, àwọn asojú pàtàkì yí ò sàkójọ ẹ̀rí, tí ó lè ní ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ìwọ àti àwọn olùfaragbá míràn.
- Wọ́n lè bèrè pé kí ìwọ se àpèjúwe ìrírí rẹ̀ níwájú ìgbìmọ̀ onígbẹ́jọ́ ìjọba àpapọ̀.
- Ìwádìí ní pípé yóò parí. Ìwádìí nàá lè gba àkókò púpọ̀ láti parí, àti pé o kò ní ní ìmúdójúìwọ̀n ní ọjọ́ sí ọjọ́ lórí ìlọsíwájú ọ̀ràn nàá. Gbogbo akitiyan ni yóò jẹ́ síse láti sọ fún ọ nípa ìsẹ̀lẹ̀ pàtàkì nínú ìwádìí, bíi mímú tàbí ìfẹ̀sùnkanni. FBI ti farajì láti máa pèsè irú àlàyé nàá fún ọ kí ó t ó di mímọ̀ fún ará ìlú, nígbàtí ó bá seése. Síbẹ̀síbẹ̀, FBI gbọ́dọ̀ sọ́ra nígbàgbogbo láti máse àfihàn àlàyé ẹlẹgẹ́ tí ó lè se ìpalára fún ìwádìí tàbí jẹ́ kí ewu pọ̀si fún agbófiró.
- Alámọ̀já olùfaragbá FBI yí ó wà láti pèsè àtìlẹ́yìn, àlàyé, àti àwọn ìtọ́kasí fún èyíkèyí ohun èlò ní ìbílẹ̀ tí àwọn olùfaragbá tí a mọ̀ lè nílò.

***Ani ti ìfisùn ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé bí wọ́n ti se ìhàlẹ̀ tàbí idẹ́rùbà kò bá yọrí sí iwadi, ó lè seése ko se ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùfaragbá òmíràn nípa kí ó ran FBI lọ́wọ́ láti tọ ojú ìpa àwọn ìhàlẹ̀ àti mọ bí ó se ń lọ.***

*ÀLÀYÉ ÌKÀNSÍ Ọ́FÌÌSÌ FBI AGBÈGBÈ LÁTI ỌWỌ́ ÌLÚ ÀTI ÌPÍNLẸ̀ NI Ó WÀ NÍ WWW.FBI.GOV. •TÍ ÌWỌ BÁ WÀ NÍNÚ EWU LỌ́WỌ́LỌ́WỌ́, PE Ẹ̀Ẹ̀SÁN, OÓKAN, OÓKAN.*